# IBI MIMỌ́ JULỌ: APẸẸRẸ IFIWỌNI
## ẸMI MIMỌ́
### Ẹksodu 26:31-34; 37:1-9; 40:20, 21, 34-38;Lefitiku 16:2;
### Iṣe Awọn Apọsteli 2:1-4; Heberu 9:6-8; 10:19-22
### ẸKỌ 74 FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Ẹ jẹ ki a fi otitọ ọkàn sunmọ tosi ni ẹ̀kún igbagbọ́, ki a si wẹ̀ ọkàn wa mọ́ kuro ninu ẹri-ọkàn buburu" (Heberu 10:22).**

**I "Ibi Mimọ́ Julọ" ninu Agọ**

1. Aṣọ ikele ni o ṣe ipinya laaarin Ibi Mimọ ati Ibi Mimọ́ Julọ, Ẹksodu 26:31-33
2. A gbe Apoti Majẹmu si Ibi Mimọ́ Julọ, Ẹksodu 37:1-5; 40:20, 21
3. Itẹ Aanu ti a fi kiki wura pẹlẹbẹ ṣe ni a fi bo Apoti Ẹri, Ẹksodu 26:34; 37:6
4. Awọn kerubu meji wà lori Itẹ Aanu, Ẹksodu 37:7-9
5. Kò si imọlẹ ti ayé ti a gbà láyè ni Ibi Mimọ́ Julọ, 1 Awọn Ọba 8;12; Ifihan 21:23; 22:5
6. Ọlọrun fi didun inu Rẹ̀ hàn nipa awọsanma ti o fara hàn loke, ati nipa ogo Rẹ̀ ti o hàn ninu Agọ Ajọ, Ẹksodu 40:34-38; 25:22; Numeri 7:89; Lefitiku 9:22-24; Orin Dafidi 99:1; Isaiah 37:16
7. Ọlọrun sọ fun Mose pe ki o kilọ fun Aarọni nitori ewu ti o wà nipa wiwọ inu Ibi Mimọ́ Julọ yatọ si gẹgẹ bi aṣẹ, Lefitiku 16:2

**II "Ibi Mimọ́ Julọ" ni Akoko ti Awọn Ọmọlẹyin Kristi**

8. Ibi Mimọ́ Julọ tọka si iriri kan ti a ti ṣeleri rẹ̀ tẹlẹ, ṣugbọn ti ki i ṣe fun igba aye Ofin, Heberu 9:1-9
9. Iriri titun naa, tí Ibi Mimọ́ Julọ jẹ apẹẹrẹ rẹ, wà fun kiki awọn ti a ti sọ di mimọ́, ẹbun iyanu yii ti Ẹmi Mimọ́ si wà fun wa lonii, Heberu 10:14-19, 22
10. Ikú Kristi ni o ṣí ọna silẹ si Ibi Mimọ́ Julọ nipa ti ẹmi, Heberu 10:20-22; Matteu 27:50, 51
11. Kristi ṣeleri Olutunu kan, O si gbadura fun awọn eniyan Rẹ̀ ki a le sọ wọn di mimọ́ ki wọn ba le ni iriri kẹta yii, Johannu 14:16-18, 26; 16:7-14; 17:6, 16-23
12. Itujade agbara nla nla ti Ẹmi Mimọ́ pẹlu ina fun igba kin-in-ni ni o mu ileri Jesu ṣẹ, Iṣe Awọn Apọsteli 1:4, 5, 8; 2:1-4
13. Awọn itujade agbara Ẹmi Mimọ́ ti o tun ṣẹlẹ, ati ileri ti Jesu ti ṣe lakọkọ, fi hàn pe iriri yii wà fun gbogbo awọn ti o ba ṣafẹri rẹ̀, o si wà fun awa tí igbẹyin ayé de ba pẹlu, Joẹli 2:21-32; Iṣe Awọn Apọsteli 2:16-21; 8:17; 10:44-46; 15:8; 19:6; 1 Kọrinti 2:13; 1 Johannu 2:20

## ALAYE

### Ọlọrun n tọ́ Awọn Eniyan Rẹ̀ Lọ

Ẹni ti n yọ̀ ninu iriri kinni ti oore-ọfẹ irapada Ọlọrun le rò pe Ọrun paapaa ti sọkalẹ tọ oun wá, tabi ki o ro pe ko si agbara iku kankan tabi ti ọrun apaadi ti o le yẹ igbagbọ́ oun tabi ti o le din ifẹ oun kù. Ṣugbọn eniyan ẹlẹran-ara ko ja mọ ohunkohun bi ko ṣe ẹni erupẹ lasan ati alailagbara. O n fẹ ohùn kan lati Ọrun wa ani ohùn Ẹmi Mimọ́, lati maa tọ́ ọ sọdọ Ọlọrun; o si ni lati maa gbọ́ ohùn yii nigba gbogbo lati maa tọ́ ọ ninu ijọsin tootọ fun Ọlọrun.

Wọn maa n wi pe ohun kan wa ninu eniyan ti o maa n ti i lati jọsin. Ṣugbọn o gba pe ki Ọlọrun tọ́ eniyan; a ni lati fi ohun ti a n pe ni isin tootọ hàn án, bi ko ṣe bẹẹ oun yoo ṣina. Ọlọrun mọ iwa abinibi yii ti o wà ninu eniyan; ki O ba le ran awọn ti wọn ti doju ọkàn wọn kọ Ọrun lọwọ, O ṣe ilana irapada, nipa eyi ti a le fi gba eniyan là kuro ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ki a si pa idibajẹ abinibi rẹ run kuro; ati lẹyin gbogbo rẹ ki a le fi Ẹmi Mimọ́ pẹlu ina wọ ọ lati ṣiṣẹ fun Ọlọrun.

### Awọn Ẹbọ ati Itumọ Wọn

Ẹbọ irekọja wà fun idariji awọn ẹṣẹ ti a mọ̀ọ́mọ̀ dá, ati awọn ti a dá nipa ainaani tabi aile ṣaapọn lati kiye si gbogbo ifẹ Ọlọrun ti o fara hàn.

Lẹyin igba naa ni ẹlẹṣẹ ti a ti dariji le mu ẹbọ sisun ti rẹ ati ẹbọ ohun jijẹ ti rẹ wá lati ya ara rẹ sọtọ niwọn bi oun ti ri i pe o yẹ ki oun sun mọ Ọlọrun si i. O tun le mu ẹbọ alaafia rẹ wá lati le tubọ ni idapọ kikun pẹlu Ọlọrun. Ṣugbọn o tun gbọdọ fi ẹbọ miiran kun iwọnyi. Ni isalẹ ọkàn rẹ ni ẹ̀ṣẹ abinibi wà, eyi ti n fẹ ẹjẹ ti a ta silẹ fun iparun rẹ. A yan ẹbọ ẹṣẹ fun eniyan lati ran an lọwọ nigba ti o ba n sun mọ Ọlọrun lati wá iriri oore ọfẹ nla keji ti i ṣe isọdimimọ́ patapata.

A ti ri i bi awọn apa kan ninu isin Agọ ti jẹ apẹẹrẹ awọn iriri wọnyii ati bi ẹjẹ awọn oniruuru ẹranko ti tọka si "ẹ̀jẹ alaiṣẹ" ti a ta silẹ nigba ti akoko Ọlọrun tó. A ti ri i pe tita ẹjẹ silẹ ṣe pataki pupọ ninu gbogbo orişiriṣi etutu fun ẹṣẹ ati irekọja wọnyii. A ti ri i pe nigba miiran a fi ẹjẹ yii sori pẹpẹ idẹ, a si ti kẹkọọ siwaju si i bi a ti ṣe etutu

nipa wiwọ́n lara ẹjẹ yii kan naa niwaju Oluwa. Lẹyin naa a ri i pe Ibi Mimọ́ ni a gbọdọ fi ẹjẹ awọn ẹbọ miiran wọ́n, niwaju aṣọ-ikele gan an, ki a si fi diẹ ninu rẹ sara iwo pẹpẹ wura. A ti ri i pe kò si apa kankan ninu ijọsin nibi ti ẹjẹ kò ti jẹ ohun pataki. Ni Ibi Mimọ́ Julọ paapaa o ṣe danindanin pe ki a fi ẹjẹ wọ́n ibẹ lati rán awọn eniyan leti pe ireti wọn kan ṣoṣo fun igbala kuro ninu idajọ Ọlọrun wà ninu ẹjẹ ti a ta silẹ dipo ẹmi wọn. Gbogbo eto ijọsin ti Agọ jẹ apẹẹrẹ ti o tọka si Ẹbọ ti n bọ wá, ani Jesu Kristi, Ẹni Ami Ororo nla nì.

## Ibugbe Ọlọrun

A pin Agọ funra rẹ si ọna meji. A fi aṣọ-ikele pin Ibi Mimọ́ Julọ ati Ibi Mimọ́ níyà lati daabo bo alufaa – ti o wá si Ibi Mimọ́ lati ṣe iṣẹ-isin rẹ ojoojumọ -- ki ifarahan Ọlọrun ti o wà lori apoti Majẹmu ninu Ibi Mimọ́ Julọ ma ba pa a run. Apoti-Majẹmu naa pẹlu ideri rẹ ti a n pe ni Itẹ-Aanu, ati awọn kerubu meji ti a fi wura lilù ṣe, ọkọọkan ni ipẹkun rẹ kin-in-ni ati keji ni ohun kan ṣoṣo ti o wà ni Ibi Mimọ́ Julọ. Oun ni ori ti gbogbo ijọsin awọn Ọmọ Israẹli rọ̀ mọ́. Nigba ti ifarahàn Ọlọrun ba wà, wọn mọ̀ pe O wà nibẹ gẹgẹ bi Alakoso, Olutọ, ati Alaabo wọn.

Igba kan ṣoṣo ti ẹni kan n wọ inu Ibi Mimọ́ Julọ, yatọ si akoko ti wọn ba fẹ ká Agọ́ lati tẹ̀ siwaju ninu irin ajo wọn, ni Ọjọ Etutu. Ni ọjọ yii olori alufaa yoo wọ inu iyara yii lọ, oun a si fi turari ati ẹjẹ rubọ fun ẹṣẹ gbogbo eniyan lapapọ gẹgẹ bi apẹẹrẹ etutu ti Kristi ṣe fun gbogbo araye (Lefitiku 16:12, 14; Heberu 9:7; 10:19, 20). Eyi ko fi ayè silẹ fun ẹnikẹni ti o ti dẹṣẹ lati má ṣe ojuṣe ti rẹ̀. Ẹni naa gbọdọ mu ẹbọ irekọja wa lati ṣe etutu fun ẹṣẹ ara rẹ.

Kò si imọlẹ ti ayé yii ni Ibi Mimọ́ Julọ. Ogo ti o ti iwaju Ọlorun wá lati aarin awọn kerubu ni imọlẹ ibẹ gẹgẹ bi a ti sọ nipa Jerusalẹmu Titun pe: “Ilu na kò si ni iwá õrùn, tabi oṣupa, lati mã tan imọlẹ si i: nitoripe ogo Ọlọrun li o ntàn imọlẹ si i, Ọdọ-Agutan si ni fitila rẹ̀” (Ifihan 21:23). **Ṣẹkina** (ogo Ọlọrun) ni Ifarahan Ọlọrun tikara Rẹ̀, eyi ti Mose ati olori alufaa maa n ri, nitori Mose pẹlu jẹ ọ̀kan ninu awọn alufaa Ọlọrun (Orin Dafidi 99:6).

Ogo Ọlọrun pọ̀ ninu Agọ nigba ti a kọkọ gbe e kalẹ, to bẹẹ ti Mose paapaa kò fi le wọle (Ẹksodu 40:35). Mose ti ba Ọlọrun sọrọ ni ẹnu ko ẹnu, boya ju ẹnikẹni lọ ti o ti gbé ori ilẹ aye. O ti ri ifarahan Ọlọrun ni ọna ti o tayọ, lori Oke Sinai nigba ti gbogbo awọn Ọmọ Israẹli sá sẹyin afi iwọnba eniyan diẹ ti o ba a lọ si ori oke. O ti duro nibi ti igbẹ ti n jo, o si ti gbọ ti Ọlọrun sọrọ lati aarin igbẹ naa. Ṣugbọn a sọ fun ni pe Ọlọrun fi ara Rẹ̀ hàn pupọ ju bẹẹ lọ ninu Agọ nigba ti a n yà a si mimọ́ to bẹẹ ti Mose paapaa kò fi le wọle.

## Apoti Majẹmu, Itẹ Aanu ati Awọn Kerubu

Ohun iyalẹnu ni Apoti Majẹmu paapaa jẹ́. Aṣayan igi ni a fi ṣe e, a si fi wura bò o, o si wà fun ipamọ orişirişi ohun iṣura mimọ́ gẹgẹ bi Ọlorun ba ti dari. Eyi ti o ṣe pataki ju lọ ni lati fi awọn walaa okuta ti a kọ Ofin Ọlorun si pamọ sinu rẹ̀.

A ti sọ nipa itẹ-Aanu pe o jẹ ideri fun Apoti-Majẹmu. Kiki wura ni a fi ṣe e. Ni ẹgbẹ kin-in-ni ati keji ti gigun rẹ ni kerubu kan wà eyi ti a fi ogidi wura ti a ti lù pẹlẹbẹ-pẹlẹbẹ ṣe, wọn doju kọ ara wọn, wọn si n wo awọn walaa Ofin ti o wà nisalẹ ninu Apoti Majẹmu. A sọ fun ni pe ọgbọ́n ti o gbà lati fi lù ogidi wura titi yo fi di pẹlẹbẹ-pẹlẹbẹ ati lati wa fi i mọ awọn kerubu meji wọnyii jẹ eyi ti o ga to bẹẹ ti o fi jẹ pe bi a ba ri awọn oniṣẹ ọnà ti o le ṣe iru nnkan bẹẹ ni ode oni wọn kò ni pọ̀ rara.

## Kristi, Itẹ-Aanu

Iwe Mimọ́ sọ fun ni (Romu 3:24, 25) pe a n dá wa lare nipa idande ti o wà ninu Kristi, Ẹni ti Ọlọrun ti gbe kalẹ lati jẹ etutu fun wa. Awọn ti o kọ ede Griki sọ fun ni pe ọrọ ti a tumọ si **etutu** tun jẹ **itẹ-aanu**. Ẹsẹ Iwe Mimọ́ yii lati inu Majẹmu Titun mu ki ohun ti Itẹ-aanu ninu Agọ duro fun hàn si wa kedere. Itẹ-aanu duro fun Kristi.

Awọn kerubu duro fun mimu idajọ Ọlọrun ṣẹ, niwọn bi o ti jẹ pe a ti mọ awọn ẹda Ọrun wọnyii pẹlu iru iṣẹ bẹẹ ninu Iwe Mimọ́. Apẹẹrẹ ribiribi ni a fi hàn wá nihin yii. Ofin Ọlọrun, ti o wà ninu Apoti majẹmu, beere pe ki a dá olukuluku ẹni ti o ba rú ofin lẹjọ. Loke Ofin naa ni awọn kerubu wọnyii ti wọn jẹ aṣoju imuṣẹ idajọ naa. Ṣugbọn Kristi, Itẹ-Aanu ti o wà ni agbede meji, mu ki a dẹwọ idajọ naa. Wo bi Ọlọrun ti mu ki ifẹ Rẹ̀ si araye hàn kedere to fun awọn Ọmọ israẹli, ati fun awa naa pẹlu, nipa awọn apẹẹrẹ wọnyii ti a ri ni Ibi Mimọ́ Julọ.

## Ifiwọni Ẹmi Mimọ́ ati Ina

Ṣugbọn a tun ri apẹẹrẹ kan gbamu kedere nipa Ibi Mimọ́ Julọ, eyi ti ẹni ti o kọ iwe Heberu tumọ. O fi hàn wa pe gẹgẹ bi pẹpẹ idẹ ti o wà ni agbala niwaju Agọ ti jẹ apẹẹrẹ idalare, ti pẹpẹ wura ninu Ibi Mimọ́ si jẹ apẹẹrẹ isọdimimọ́, Ibi Mimọ Julọ pẹlu Ẹmi ati ifarahàn Ọlọrun nibẹ nigba gbogbo jẹ apẹẹrẹ ifiwọni Ẹmi Mimọ́ ati iná.

Iriri iyanu yii ti a kọkọ fi fun araye ni Ọjọ Pẹntekọsti ti o tẹle iku Kristi ni Kalfari, jẹ àmi pataki ti o fi akoko Ihinrere – igbà ti Ijọ Kristi, hàn yatọ. Ifiwọni Ẹmi Mimọ́ wá pẹlu “ogo” ti a sọtẹlẹ pe yoo tẹle iku Kristi, ogo ti awọn wolii paapaa ti fi tọkantọkan ṣafẹri, ti awọn angẹli Ọrun pẹlu si n fẹ lati wà (1 Peteru 1:9-12). Ẹmi Mimọ́ ni Olutunu ti Jesu sọ pe Oun yoo rán wá lẹyin ti Oun ba ti goke lọ sọdọ Baba (Johannu 16:7). A ko i ti fi I fun awọn ti Majẹmu laelae nitori a ko i ti ṣí ọ̀na si Ibi Mimọ́ Julọ silẹ (Heberu 9:8). Ṣugbọn nigba ti Jesu ku ti aṣọ ikele Tẹmpili si faya, ọna ṣi silẹ fun gbogbo ẹni ti o wá lati igba naa pẹlu igboya lati wọ inu Ibi Mimọ́ Julọ ti ẹmi, ani iriri kẹta ti o daju ninu eto Ọlọrun fun igbala eniyan (Heberu 10:19-22).

A tun fi hàn wá dajudaju pe a kò le ṣai ni isọdimimọ́ ki Ẹmi Mimọ́ to le wọ inu ọkàn wa lati maa gbé ibẹ ni ẹ̀kún rẹrẹ (Heberu 10:12-22; fi Heberu 2:11 we Iṣe Awọn Apọsteli 2:1). Awọn wolii igba Majẹmu Laelae jẹ awọn ti a ti sọ di mimọ́ (Isaiah 6:1-7), ṣugbọn wọn ko ni ifiwọni Ẹmi Mimọ́, nitori a ti ri i pe wọn sọtẹlẹ nipa rẹ wọn si ṣafẹri rẹ ṣugbọn wọn kò le ri iriri naa nitori a ko i ti ran an sọkalẹ (1 Peteru 1:9-12; Heberu 9:8).

A rọ̀ wa lati wọ inu Ibi Mimọ́ Julọ yii lai jafara (Heberu 10:22); nitori bẹẹ a le sọ pe ki i ṣe apẹẹrẹ Ọrun rara, gẹgẹ bi awọn miiran ti n kọ́ ni, ṣugbọn o jẹ apẹẹrẹ iriri kan ti a le fi fun wa ni igba aye wa isisiyii. O hàn nigba naa pe eyi tun jẹ omiran ninu awọn koko ẹkọ nlá nlà wọnni ninu Iwe Mimọ́ ti a gbe kalẹ lati ṣe amọna awọn eniyan lọ sinu otitọ Ọlọrun lẹkun rẹ́rẹ́. Nihin, ninu awọn igbesẹ kin-in-ni ninu eto Ọlọrun lati ibẹrẹ pẹpẹ ni a ri apẹẹrẹ awọn iriri Onigbagbọ mẹtẹẹta tí awa ti a wà ni akoko ti Ijọ Kristi le ri gba.

"Ẹ jẹ ki a fi otitọ ọkàn sunmọ tosi ni ẹ̀kún igbagbọ́" (Heberu 10:22). Ẹ jẹ ki a ri daju pe " a di ijẹwọ ireti wa mu ṣinṣin li aiṣiyemeji". Ẹ jẹ ki a kiye sara pe a kò kọ "ipejọpọ ara wa" silẹ ṣugbọn ki a maa gba ara wa niyanju lojoojumọ lati le ba Ọlọrun rin timọtimọ sii ki a si le tipẹlẹ mọ Ọn siwaju ati siwaju bi a ti ri i pe ọjọ bibọ Kristi n sun mọ etile.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni awọn ohun ti a fi si Ibi Mimọ́ Julọ? Ṣe alaye nipa ọkọọkan wọn.
2. Apẹẹrẹ ki ni ọkọọkan wọn jẹ́, ki ni wọn si duro fún?
3. Ki ni pin Agọ naa si meji? Sọ bi o ti ri.
4. Apẹẹrẹ ki ni Ibi Mimọ́ jẹ́?
5. Ki ni apapọ Ibi Mimọ́ Julọ duro fún?
6. Nibo ni imọlẹ ti o wà ni Ibi Mimọ́ Julọ ti wá?
7. Nigba wo ni a kọkọ mu ohun ti Ibi Mimọ́ Julọ duro fún ṣẹ?
8. Sọ nipa awọn igba miiran ti a mu un ṣẹ titi di ọjọ oni?
9. Bawo ni Iwe Mimọ́ ṣe sọ ọ fun ni pe a gbọdọ kọkọ ni isọdimimọ́ ki a to le gba ifiwọni Ẹmi Mimọ́?
10. Iṣẹlẹ nla wo ni o ṣẹlẹ eyi ti o ṣí ọna fun gbogbo wa lati wọ Ibi Mimọ́ Julọ nipa ti Ẹmi?